*Tí ìwé-pélébé yìí bá wúlò fún ọ, jọ̀wọ́ ṣàjọpín rẹ̀ pẹ̀lú ẹlòmíràn.*

**DIVINE LITERATURE INTERNATIONAL**

*~ À ń tan Ìhìnrere Káàrí Aiyé*

**www.divineliterature.org**
**www.doveletters.org**

Divine Literature International ni òǹkọ̀wé ìwé-pélébé yìí. Wọ́n sì mú u wá fún pínpín ọ̀fẹ́, gẹ́gẹ́ bí Olúwa ṣe ń pèsè. Àwọn Ìwé-pélébé wa kì í ṣe fún títà. Jọ̀wọ́ kàn sí wa nípasẹ̀ àwọn ojúlé wẹ̀ẹ̀bù wa tí ẹnikẹ́ni bá ń gbìyànjú láti tà á fún ọ.

©Divine Literature International 2023



# Mo ti ní Ìgbàlà! Kí ló Kàn?

Káàbọ̀ sí agboolé Ọlọ́run, olùfẹ́! Ní kété tí a bá ti rí ìgbàlà gbà nípasẹ̀ Jésù Krístì, a ó bẹ̀rẹ̀ sí ṣiṣẹ́ ìgbàlà náà (Fílípì 2:12). Ó ṣe pàtàkì láti ṣàlàyé fún ọ pé, a ò kíí ṣiṣẹ́ láti ní ìgbàlà, ṣùgbọ́n a ní láti ṣiṣẹ́ ìgbàlà wa yọrí nígbà tí a bá ti ní i. Ẹ̀mí mímọ́ ni ó ń ran ènìyàn lọ́wọ́ láti ṣe èyí. Ọpọ ènìyàn ló ti gbàgbọ́ wípé, gbígba Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà nìkan ni ohun tí a ní láti ṣe kí a rí Ọ̀run wọ̀, kí a sì ní Ìyè Àìnípẹ̀kun ohun yòówù irú ìgbésí aiyé tí a yàn láti gbé. Àmọ́, rárá; kò rí bẹ́ẹ̀. Òtítọ́ ibẹ̀ ni pé, ohun Ìgbàlà kò parí síbi sísọ Àdúrà Ìgbàlà. Ṣíṣe ìpinnu láti gba Jésù Krístì jẹ́ ìbẹ̀rẹ̀ ìbáṣepọ̀ onídùnnú tí a ní pẹ̀lú Ọlọ́run. Bákan náà Krístì kìí kẹ̀yìn sí ènìyàn tí ó ti gbàágbọ́, tí ó sì ti jọ̀wọ́ aiyé rẹ fún un (Jòhánù 6:37, Mátíù 18: 11-13). Bí ó tilẹ̀ jẹ́ bẹ́ẹ̀, ó ṣeé ṣe kí ènìyàn yí padà kúrò lọdọ Krístì ní tààràtà tàbí láìṣe tààràtà, nígbà tí ẹni náà bá kọ láti



tẹrí ba fún ọlá àṣẹ àti ipò Rẹ̀, pátápátá. Èyí túmọ̀ sí pé, ẹni náà ti kúrò nínú Ìgbàgbọ́ nípa yíyàn tirẹ̀. Jésù Krístì sọ wípé, kìí ṣe gbogbo ènìyàn tí wọ́n sọ pé àwọ́n gbàágbọ́, àwọ́n sì ń tẹ̀ lé e ni yóò rí Ọ̀run wọ̀, àyàfi bí wọ́n bá ṣe ìfẹ́ Ọlọ́run Bàbá (Mátíù 7:21-27). Ó máa ń gba àkókò kí ènìyàn tó débi tí yóò ṣe ìpinnu láti yà kúrò lọdọ Rẹ̀, ṣùgbọ́n ó ń ṣẹlẹ̀. Bíbélì sọ̀rọ̀ nípa rẹ̀ bíi: “*Ajá tí ó yí padà sí èébì rẹ̀*” (2 Pétérù 2:20-22). Bí ó ti wù kí ó rí, nǹkan ìdùnnú ni pé, inú Bàbá wa Aláàánú àti Onífẹ̀ẹ́ máa ń dùn láti gbà wá padà nígbà tí a bá rìn lọ ṣùgbọ́n tí a padà sọ́dọ̀ Rẹ̀ bíi ọmọ onínàákúnàá tí Krístì sọ̀rọ̀ nipa rẹ̀ nínú Bíbélì (wo Lúùkù 15:11-32).

Ó ṣeé ṣe ko máa rò báyìí: *“Mo ti ní Ìgbàlà. Kíni kí n ṣe?”*

(i) **Dáríji Ara Rẹ:** O ti di ènìyàn tuntun báyìí. Ọlọ́run fi bí Ó ṣe nífẹ̀ẹ́ rẹ tó hàn,



*Tí ìwé-pélébé yìí bá wúlò fún ọ, jọ̀wọ́ ṣàjọpín rẹ̀ pẹ̀lú ẹlòmíràn.*

**DIVINE LITERATURE INTERNATIONAL**

*~ À ń tan Ìhìnrere Káàrí Aiyé*

**www.divineliterature.org**
**www.doveletters.org**

Divine Literature International ni òǹkọ̀wé ìwé-pélébé yìí. Wọ́n sì mú u wá fún pínpín ọ̀fẹ́, gẹ́gẹ́ bí Olúwa ṣe ń pèsè. Àwọn Ìwé-pélébé wa kì í ṣe fún títà. Jọ̀wọ́ kàn sí wa nípasẹ̀ àwọn ojúlé wẹ̀ẹ̀bù wa tí ẹnikẹ́ni bá ń gbìyànjú láti tà á fún ọ.

©Divine Literature International 2023



# Mo ti ní Ìgbàlà! Kí ló Kàn?

Káàbọ̀ sí agboolé Ọlọ́run, olùfẹ́! Ní kété tí a bá ti rí ìgbàlà gbà nípasẹ̀ Jésù Krístì, a ó bẹ̀rẹ̀ sí ṣiṣẹ́ ìgbàlà náà (Fílípì 2:12). Ó ṣe pàtàkì láti ṣàlàyé fún ọ pé, a ò kíí ṣiṣẹ́ láti ní ìgbàlà, ṣùgbọ́n a ní láti ṣiṣẹ́ ìgbàlà wa yọrí nígbà tí a bá ti ní i. Ẹ̀mí mímọ́ ni ó ń ran ènìyàn lọ́wọ́ láti ṣe èyí. Ọpọ ènìyàn ló ti gbàgbọ́ wípé, gbígba Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà nìkan ni ohun tí a ní láti ṣe kí a rí Ọ̀run wọ̀, kí a sì ní Ìyè Àìnípẹ̀kun ohun yòówù irú ìgbésí aiyé tí a yàn láti gbé. Àmọ́, rárá; kò rí bẹ́ẹ̀. Òtítọ́ ibẹ̀ ni pé, ohun Ìgbàlà kò parí síbi sísọ Àdúrà Ìgbàlà. Ṣíṣe ìpinnu láti gba Jésù Krístì jẹ́ ìbẹ̀rẹ̀ ìbáṣepọ̀ onídùnnú tí a ní pẹ̀lú Ọlọ́run. Bákan náà Krístì kìí kẹ̀yìn sí ènìyàn tí ó ti gbàágbọ́, tí ó sì ti jọ̀wọ́ aiyé rẹ fún un (Jòhánù 6:37, Mátíù 18: 11-13). Bí ó tilẹ̀ jẹ́ bẹ́ẹ̀, ó ṣeé ṣe kí ènìyàn yí padà kúrò lọdọ Krístì ní tààràtà tàbí láìṣe tààràtà, nígbà tí ẹni náà bá kọ láti

2

tẹrí ba fún ọlá àṣẹ àti ipò Rẹ̀, pátápátá. Èyí túmọ̀ sí pé, ẹni náà ti kúrò nínú Ìgbàgbọ́ nípa yíyàn tirẹ̀. Jésù Krístì sọ wípé, kìí ṣe gbogbo ènìyàn tí wọ́n sọ pé àwọ́n gbàágbọ́, àwọ́n sì ń tẹ̀ lé e ni yóò rí Ọ̀run wọ̀, àyàfi bí wọ́n bá ṣe ìfẹ́ Ọlọ́run Bàbá (Mátíù 7:21-27). Ó máa ń gba àkókò kí ènìyàn tó débi tí yóò ṣe ìpinnu láti yà kúrò lọdọ Rẹ̀, ṣùgbọ́n ó ń ṣẹlẹ̀. Bíbélì sọ̀rọ̀ nípa rẹ̀ bíi: “*Ajá tí ó yí padà sí èébì rẹ̀*” (2 Pétérù 2:20-22). Bí ó ti wù kí ó rí, nǹkan ìdùnnú ni pé, inú Bàbá wa Aláàánú àti Onífẹ̀ẹ́ máa ń dùn láti gbà wá padà nígbà tí a bá rìn lọ ṣùgbọ́n tí a padà sọ́dọ̀ Rẹ̀ bíi ọmọ onínàákúnàá tí Krístì sọ̀rọ̀ nipa rẹ̀ nínú Bíbélì (wo Lúùkù 15:11-32).

Ó ṣeé ṣe ko máa rò báyìí: *“Mo ti ní Ìgbàlà. Kíni kí n ṣe?”*

(i) **Dáríji Ara Rẹ:** O ti di ènìyàn tuntun báyìí. Ọlọ́run fi bí Ó ṣe nífẹ̀ẹ́ rẹ tó hàn,

3

nígbà tí Ó fi Ọmọ Rẹ̀ kan ṣoṣo fún ọ, láti kú dípò ko jìyà fún àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ.

*Nítorí náà, bí ẹnikẹ́ni bá wà nínú Krístì, ó ti di ẹ̀dá tuntun: ohun àtijọ́ ti kọjá lọ; kíyèsi i, ohun tuntun ti dé (2 Kọ́ríńtì 5:17).*

Àwọn ohun àtijọ́ tí ó wà nínú ọ̀rọ̀ yìí náà ní àwọn ìfẹ́kúfẹ̀ẹ́ ẹ̀ṣẹ̀ àti ìfẹ́ onígbòónára fún ẹ̀ṣẹ̀ tí o ní tẹ́lẹ̀. Ìsọdẹrú rẹ sí wọn ti bàjẹ́ nígbà tí o gba Jésù Krístì. Ìwọ kì í ṣe ti ara rẹ mọ́. O ti di tẹ́mpìlì Ẹ̀mí Mímọ́. Ó sì ti ń gbé nínú rẹ báyìí (1 Kọ́ríńtì 6:19).

(ii) **Ṣe ìpinnu láti máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́:** Èyí jẹ́ nǹkan pàtàkì gidi, olùfẹ́ (Hébérù 12:14). Gbàrà tí o bá ti pinnu láti máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́, ohun gbogbo yóò bẹ̀rẹ̀ sí ní bọ́ síra láìtàsé. Ẹ̀mí mímọ́ yóò máa ràn ẹ́ lọ́wọ́, bí o ṣe ń fọwọ́sowọ́pọ̀ pẹ̀lú Rẹ̀.



(iii) **Wá Bíbélì kan, kí o sì lo àkókò pẹ̀lú Ọlọ́run:** Dá àṣa kíka Bíbélì àti gbígbàdúrà sí Ọlọ́run ní gbogbo ìgbà. Ó lè máà jẹ́ fún ìgbà pípẹ́ ní ìbẹ̀rẹ̀, ṣùgbọ́n bí o ṣe ń dàgbà nípa ti ẹ̀mí, wàá rí i pé àkókò tí ò ń lò pẹ̀lú Ọlọ́run ń gùn sí i. O lè lo Bíbélì tí ó wà lórí ayélujára fún ìgbà díẹ̀, kí o tó ra tìrẹ. Ṣàbẹ̀wò sí àwọn ojú ìwé wọ̀nyí lórí ojúlé wẹ̀ẹ̀bù wa: *Ka Bíbélì lórí Ayélujára* àti *Tẹ́tí sí Bíbélì lórí Ayélujára*, fún Bíbélì ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ èdè. Ó ṣe pàtàkì fún ọ láti máa ka Bíbélì rẹ lójoojúmọ́ kí o lè lóye àwọn ẹ̀kọ́ Krístì dáadáa láti mú u gbé. Kíka Bíbélì yóò ràn ọ́ lọ́wọ́ láti di aṣẹ́gun ní gbogbo ọ̀nà. Àwọn ìlérí Ọlọ́run sí ọ wà nínú rẹ, pẹ̀lú. Bíbélì (èyí tí í ṣe Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run) yóò ràn ọ́ lọ́wọ́ láti dúró ṣinṣin nígbà tí èṣù bá ń pa iró rẹ, tí ó sì ń gbìyànjú láti tàn ọ́ padà sínú ẹ̀ṣẹ̀ àti ìgbésí aiyé ìbànújẹ́ tí o ti sá jáde.



Bíbélì jẹ́ ohun-ìjà alágbára tí gbogbo onígbàgbọ́ rọ̀ mọ́ láti ṣẹ́gun. Idi èyí ni a fi ń pè é ní, *Idà Ẹ̀mí* (Éfésù 6:17). Gbàdúrà sí Olúwa fún òye, kí o sì ṣàṣàrò lórí ohun tí o bá kà. Àwọn ibì kan wà nínú Bíbélì tí o lè máà ní òye rẹ lákọ̀ọ́kọ́. Lẹ́ẹ̀kan sí i, gbàdúrà fún òye. Bí àkókò ṣe ń lọ, wàá bẹ̀rẹ̀ sí ní òye ohun tí ò ń kà, ìwọ yóò sì máa jàǹfààní rẹ̀, pẹ̀lú.

(iv) **Wá ṣọ́ọ̀ṣì tàbí ibi ìpàdé Krìstẹ́nì:** Ó ṣe pàtàkì fún ọ láti máa gba ẹ̀kọ́ tí ó múnádóko lórí ìrìn àjò Krìstẹ́nì yìí. Wá ṣọ́ọ̀ṣì tàbí ibi ìpàdé Krìstẹ́nì kan ní agbègbè rẹ tí o ti lè máa jọ́sìn, tí o sì máa dàgbà nínú ẹ̀mí, pẹ̀lú.

(v) **Ní ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn tí ó wà nínú Krístì:** Darapọ̀ mọ́ àwọn ọmọlẹ́yìn Krístì òtítọ́. Wọn yóò dáhùn àwọn ìbéèrè mìíràn tí o lè ní. Wọ́n á sì jẹ́ àtìlẹ́yìn fún ọ lórí ìrìn-àjò Krìstẹ́nì rẹ.



(vi) **Ṣe Ìrìbọmi:** Bẹ̀rẹ̀ láti ṣe baptisì nípasẹ̀ rírì bọ inú omi, gẹ́gẹ́ bí Jésù Krístì ti ṣe àpẹẹrẹ rẹ̀ (Mátíù 3:13-17), tí ó sì pàṣẹ (Mátíù 28:19). Nípasẹ̀ baptisì, à ń dá ara wa mọ̀ pẹ̀lú ikú àti àjíǹde Krístì. Ìrìbọmi tún ń tọ́ka sí ikú àti ìsìnkú aiyé ẹ̀ṣẹ̀ wa, àjíǹde wa gẹ́gẹ́ bí ènìyàn tí Ọlọ́run ti dáríjì nípasẹ̀ Krístì (Kólósè 2:10-13); kíkọ̀ sílẹ̀ ẹ ìmọtara-ẹni-nìkan, ìgbéraga, ìgbà wa àtijọ́; àti fífi gbogbo ohun ìní wa lélẹ̀ fún un. Aṣáájú ṣọ́ọ̀ṣì tàbí ibi ìpàdé Krìstẹ́nì rẹ yóò túbọ̀ ṣàlàyé *Ìrìbọmi* fún ọ.

(vii) **Jẹ́ Ẹlẹ́rìí Olóòótọ́ fún Olúwa:** Sọ fún àwọn ènìyàn nípa ìgbàgbọ́ tuntun rẹ nínú Jésù Krístì. Jẹ́ kí wọ́n mọ̀ nípa Oore-ọ̀fẹ́ Ìgbàlà Rẹ̀, àti pàtàkì Ìgbàlà. Ṣàbẹ̀wò sí ojú ìwé *Àwọn Oríṣì Ìjíhìnrere* lórí ojúlé wẹ̀ẹ̀bù wa fún ìmọ̀ràn nípa bí o ṣe lè jẹ́ Ẹlẹ́rìí fún Olúwa. O sì lè ṣe ìgbàsílẹ̀, tàbí kí o béèrè fún àwọn ìwé pélébé wa fún Ìhìnrere, lọ́fẹ̀ẹ́. A kí ọ!



nígbà tí Ó fi Ọmọ Rẹ̀ kan ṣoṣo fún ọ, láti kú dípò ko jìyà fún àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ.

*Nítorí náà, bí ẹnikẹ́ni bá wà nínú Krístì, ó ti di ẹ̀dá tuntun: ohun àtijọ́ ti kọjá lọ; kíyèsi i, ohun tuntun ti dé (2 Kọ́ríńtì 5:17).*

Àwọn ohun àtijọ́ tí ó wà nínú ọ̀rọ̀ yìí náà ní àwọn ìfẹ́kúfẹ̀ẹ́ ẹ̀ṣẹ̀ àti ìfẹ́ onígbòónára fún ẹ̀ṣẹ̀ tí o ní tẹ́lẹ̀. Ìsọdẹrú rẹ sí wọn ti bàjẹ́ nígbà tí o gba Jésù Krístì. Ìwọ kì í ṣe ti ara rẹ mọ́. O ti di tẹ́mpìlì Ẹ̀mí Mímọ́. Ó sì ti ń gbé nínú rẹ báyìí (1 Kọ́ríńtì 6:19).

(ii) **Ṣe ìpinnu láti máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́:** Èyí jẹ́ nǹkan pàtàkì gidi, olùfẹ́ (Hébérù 12:14). Gbàrà tí o bá ti pinnu láti máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́, ohun gbogbo yóò bẹ̀rẹ̀ sí ní bọ́ síra láìtàsé. Ẹ̀mí mímọ́ yóò máa ràn ẹ́ lọ́wọ́, bí o ṣe ń fọwọ́sowọ́pọ̀ pẹ̀lú Rẹ̀.

4

(iii) **Wá Bíbélì kan, kí o sì lo àkókò pẹ̀lú Ọlọ́run:** Dá àṣa kíka Bíbélì àti gbígbàdúrà sí Ọlọ́run ní gbogbo ìgbà. Ó lè máà jẹ́ fún ìgbà pípẹ́ ní ìbẹ̀rẹ̀, ṣùgbọ́n bí o ṣe ń dàgbà nípa ti ẹ̀mí, wàá rí i pé àkókò tí ò ń lò pẹ̀lú Ọlọ́run ń gùn sí i. O lè lo Bíbélì tí ó wà lórí ayélujára fún ìgbà díẹ̀, kí o tó ra tìrẹ. Ṣàbẹ̀wò sí àwọn ojú ìwé wọ̀nyí lórí ojúlé wẹ̀ẹ̀bù wa: *Ka Bíbélì lórí Ayélujára* àti *Tẹ́tí sí Bíbélì lórí Ayélujára*, fún Bíbélì ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ èdè. Ó ṣe pàtàkì fún ọ láti máa ka Bíbélì rẹ lójoojúmọ́ kí o lè lóye àwọn ẹ̀kọ́ Krístì dáadáa láti mú u gbé. Kíka Bíbélì yóò ràn ọ́ lọ́wọ́ láti di aṣẹ́gun ní gbogbo ọ̀nà. Àwọn ìlérí Ọlọ́run sí ọ wà nínú rẹ, pẹ̀lú. Bíbélì (èyí tí í ṣe Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run) yóò ràn ọ́ lọ́wọ́ láti dúró ṣinṣin nígbà tí èṣù bá ń pa iró rẹ, tí ó sì ń gbìyànjú láti tàn ọ́ padà sínú ẹ̀ṣẹ̀ àti ìgbésí aiyé ìbànújẹ́ tí o ti sá jáde.

5

Bíbélì jẹ́ ohun-ìjà alágbára tí gbogbo onígbàgbọ́ rọ̀ mọ́ láti ṣẹ́gun. Idi èyí ni a fi ń pè é ní, *Idà Ẹ̀mí* (Éfésù 6:17). Gbàdúrà sí Olúwa fún òye, kí o sì ṣàṣàrò lórí ohun tí o bá kà. Àwọn ibì kan wà nínú Bíbélì tí o lè máà ní òye rẹ lákọ̀ọ́kọ́. Lẹ́ẹ̀kan sí i, gbàdúrà fún òye. Bí àkókò ṣe ń lọ, wàá bẹ̀rẹ̀ sí ní òye ohun tí ò ń kà, ìwọ yóò sì máa jàǹfààní rẹ̀, pẹ̀lú.

(iv) **Wá ṣọ́ọ̀ṣì tàbí ibi ìpàdé Krìstẹ́nì:** Ó ṣe pàtàkì fún ọ láti máa gba ẹ̀kọ́ tí ó múnádóko lórí ìrìn àjò Krìstẹ́nì yìí. Wá ṣọ́ọ̀ṣì tàbí ibi ìpàdé Krìstẹ́nì kan ní agbègbè rẹ tí o ti lè máa jọ́sìn, tí o sì máa dàgbà nínú ẹ̀mí, pẹ̀lú.

(v) **Ní ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn tí ó wà nínú Krístì:** Darapọ̀ mọ́ àwọn ọmọlẹ́yìn Krístì òtítọ́. Wọn yóò dáhùn àwọn ìbéèrè mìíràn tí o lè ní. Wọ́n á sì jẹ́ àtìlẹ́yìn fún ọ lórí ìrìn-àjò Krìstẹ́nì rẹ.

6

(vi) **Ṣe Ìrìbọmi:** Bẹ̀rẹ̀ láti ṣe baptisì nípasẹ̀ rírì bọ inú omi, gẹ́gẹ́ bí Jésù Krístì ti ṣe àpẹẹrẹ rẹ̀ (Mátíù 3:13-17), tí ó sì pàṣẹ (Mátíù 28:19). Nípasẹ̀ baptisì, à ń dá ara wa mọ̀ pẹ̀lú ikú àti àjíǹde Krístì. Ìrìbọmi tún ń tọ́ka sí ikú àti ìsìnkú aiyé ẹ̀ṣẹ̀ wa, àjíǹde wa gẹ́gẹ́ bí ènìyàn tí Ọlọ́run ti dáríjì nípasẹ̀ Krístì (Kólósè 2:10-13); kíkọ̀ sílẹ̀ ẹ ìmọtara-ẹni-nìkan, ìgbéraga, ìgbà wa àtijọ́; àti fífi gbogbo ohun ìní wa lélẹ̀ fún un. Aṣáájú ṣọ́ọ̀ṣì tàbí ibi ìpàdé Krìstẹ́nì rẹ yóò túbọ̀ ṣàlàyé *Ìrìbọmi* fún ọ.

(vii) **Jẹ́ Ẹlẹ́rìí Olóòótọ́ fún Olúwa:** Sọ fún àwọn ènìyàn nípa ìgbàgbọ́ tuntun rẹ nínú Jésù Krístì. Jẹ́ kí wọ́n mọ̀ nípa Oore-ọ̀fẹ́ Ìgbàlà Rẹ̀, àti pàtàkì Ìgbàlà. Ṣàbẹ̀wò sí ojú ìwé *Àwọn Oríṣì Ìjíhìnrere* lórí ojúlé wẹ̀ẹ̀bù wa fún ìmọ̀ràn nípa bí o ṣe lè jẹ́ Ẹlẹ́rìí fún Olúwa. O sì lè ṣe ìgbàsílẹ̀, tàbí kí o béèrè fún àwọn ìwé pélébé wa fún Ìhìnrere, lọ́fẹ̀ẹ́. A kí ọ!

7